# A TÚN MAJẸMU NAA DÁ
## Ẹksodu 34:1-35
## ẸKỌ 69 FUN AGBA

**AKỌSORI:"OLUWA si rekọja niwaju rẹ̀, o si nkepè, OLUWA, OLUWA, Ọlọrun, alãnu ati olore-ọfẹ, onipamọra, ati ẹniti o pọ̀ li ore ati otitọ" (Ẹksodu 34:6).**

**I A Tún Majẹmu Naa Dá ni Oke Sinai**

1 A paṣẹ fun Mose pe ki oun nikan gun Oke Sinai wá ki a ba le tún ofin Ọlọrun kọ sara walaa okuta lẹẹkan si i, Ẹksodu 34:1-4; Deuteronomi 10:1-4

2 Ọlọrun jẹri si yíyan Mose lẹẹkan si i nipa jijẹ ki iwa pẹlu ọla nla Ọlọrun di mimọ̀ fun un ni ọna ti o tobi ju ti atẹyinwa; gẹgẹ bi a ti ṣeleri ṣiwaju, Ẹksodu 34:5-7; 33:19; Jakọbu 4:8; Orin Dafidi 73:28; Heberu 10:22

3 Mose fi tọwọtọwọ sin Ọlọrun, o si fi ọkàn tutu ati ẹmi aimọ-ti-ara-rẹ̀ nikan hàn nipa lilo anfaani akọtun oju rere Ọlọrun ti o tun ri gbà yii lati bẹbẹ fun awọn Ọmọ Israẹli, Ẹksodu 34:8, 9; Deuteronomi 10:10, 11

4 Ọlọrun dahun ibeere Mose, O bá Israẹli dá majẹmu, imuṣẹ eyi ti o duro lori igbọran wọn si Ofin Rẹ̀, Ẹksodu 34:10, 11; Deuteronomi 10:12-22; 11:1-32

**II Awọn Nnkan Wọnni ti a Beere ninu Majẹmu Naa**

1. Akọkọ ni fifi ara mọ́ Ọlọrun timọtimọ, ati sisin Oun nikan ṣoṣo, Ẹksodu 34:12-17; Matteu 22:36-39; Luku 14:26-33; 5:27, 28; 18:29, 30; Filippi 3:8
2. Lati jẹ ki isin Ọlọrun maa wà niwaju wọn nigba gbogbo, a paṣẹ Ajọ-Irekọja, Ajọ Pẹntekọsti, Ajọ Agọ, iyọọda ati irapada akọbi, mimu akọso eso wá, ati pipa ọjọ Isinmi mọ́ ni ọsọọsẹ, Ẹksodu 34:18-28; Lefitiku 23:1-44; Numeri 9:1-14; Deuteronomi 16:1-17

**I Sisọ Majẹmu Naa fun Awọn Ọmọ Israẹli**

3. Awọ oju Mose n dán fun ogo Ọlọrun nitori o ba Ọlọrun sọrọ pẹ́ titi, eyi ti i ṣe ẹri pe wolii Ọlọrun ni i ṣe, Ẹksodu 34:29, 30; Matteu 17:2, 3; Deuteronomi 34:10
4. Mose gẹgẹ bi iranṣẹ Ọlọrun tootọ sọ gbogbo ọrọ Oluwa fun awọn Ọmọ Israẹli, Ẹksodu 34:31, 32; Isaiah 62:6; Iṣe Awọn Apọsteli 6:4; 20:28; 1 Timoteu 4:6; 1 Peteru 5:2-4; 4:10; 1 Kọrinti 4:1, 2
5. Nitori didan awọ oju Mose, o ni lati fi iboju bo oju rẹ̀ nigba ti o ba n ba awọn Ọmọ Israẹli sọrọ, Ẹksodu 34:33-35; 2 Kọrinti 3:7-18

## ALAYE

**Ohun ti a le ri kọ́ lara Awọn Ọmọ Israẹli**

Ninu ọpọlọpọ awọn ẹkọ wa atẹyinwa, a ti ka ohun ti o ba ni ninu jẹ pupọ nipa itan igbesi-aye awọn Ọmọ Israẹli. Nigba ti wọn wà ni ẹba Oke Sinai, wọn ti gbọ́ ohùn Ọlọrun ṣugbọn wọn ti fà sẹyin, wọn si kọ̀ lati jẹ ki O kọ Ofin Rẹ̀ si aya wọn (Owe 3:3; 7:3; Jeremiah 31:31-34).

Nigba ti Mose pẹ́ lati pada lati Oke Sinai awọn Ọmọ Israẹli yí pada si ibọriṣa, wọn ṣe ẹgbọrọ maluu wura wọn si sin in; Ọlọrun si jẹ wọn niya gidigidi nitori eyi. O daju pe ijiya yii pọ̀ pupọ rekọja ohun ti awọn Ọmọ Israẹli rò tẹlẹ, nitori ironupiwada wọn kò to lati mu ki wọn tun ri gbogbo ibukun ti wọn ti n gbadun tẹlẹtẹlẹ gba pada. Mose ni lati bẹbẹ fun wọn léraléra ki gbogbo awọn anfaani iyebiye ti Ọlọrun ti pinnu ba le tun pada jẹ ti wọn. Bi a ti n ṣe akiyesi ibalo Ọlọrun pẹlu awọn Ọmọ Israẹli, lati igba ti O ti kọ̀ wọn silẹ nigba ti Ọlọrun kọkọ sọ fun Mose nipa ẹ̀ṣẹ ibọriṣa wọn titi lọ de igba ti wọn tun tẹsiwaju ni irin-ajo wọn si Kenaani (Numeri 10:11-13), awọn kókó otitọ ti o tobi ti o si ṣe iyebiye fi ara hàn.

Ekinni, a ri ibi ti o wà ninu kikọ Ọlọrun silẹ fun eredi-keredi, ati ṣiṣe aigbọran lọnakọna si Ofin Ọlọrun. Lọna keji, a ri i pe ohun ti yoo gbẹyin iru kikọ Ọlọrun silẹ bẹẹ lọ titi ni pe Ọlọrun yoo kọ ẹlẹṣẹ naa silẹ; ati pe ironupiwada pẹlu gbogbo ọkàn ni o le mu ki Ọlọrun yí iwa pada lati mu ẹlẹṣẹ naa bọ̀ sinu oju rere Rẹ̀. Lọna kẹta, a ri i gẹgẹ bi Mose ti fi iwa ati iṣe alakoso tootọ hàn, ẹni ti ko wá ire ti ara rẹ̀, ti o si n bẹbẹ fun ire awọn ti Ọlọrun fi i ṣe alakoso fun. Lọna kẹrin, a ri i bi o ti ṣe pataki to pe ki Ọlọrun maa wà pẹlu wa nigba gbogbo ati pẹlu awọn ibukun ti ara ati ti ẹmi ti Israẹli i ba padanu bi o ba ṣe pe Mose kò bẹbẹ fun wọn.

Lọna karun-un, a ri i pe Ọlọrun maa n dán awọn eniyan Rẹ̀ wò, ani awọn ti Rẹ̀ ti o yàn ti O si ti kọ́, ki awọn tikara wọn ba le mọ daju ohun ti ó wà lọkan wọn. Lọna kẹfa, a ri i gbangba pe Ọlọrun maa n sun mọ awọn ti o ba sun mọ Ọn, ati pe iṣisẹ kọọkan ti a ba gbe lati sun mọ Ọn i baa ṣe lati ori oke, tabi lati isalẹ afonifoji, yoo mu ki a ri ifihan orukọ nla Rẹ̀ ati iwa ọla nla Rẹ̀ ti o logo. Lọna keje, a ri awọn nnkan ti o le fẹsẹ majẹmu wa pẹlu Ọlọrun mulẹ: jijẹ oloootọ ni fifi ara mọ Ọlọrun ati sisin In, gbigbọran si aṣẹ Rẹ̀ lai tọpinpin idi rẹ̀, mimu anfaani nnkan wọnni ti O fi fun ni ti o le mu wa dagba ninu oore-ọfẹ lò. Lakotan, ninu itan igbesi aye awọn Ọmọ Israẹli ti a ka

yii (1 Kọrinti 10:1-11) a ri apẹẹrẹ ogo ti yoo jẹ ti wa nigba ti a ba fi gbogbo ọkàn wa tẹle Ọlọrun, ti a doju kọ iṣẹ ti Ọlọrun rán wa lati boju to laaarin ara wa si ara wa, ti a si n fi tọkantọkan ati aimọ-ti-ara-ẹni-nikan bẹbẹ fun awọn ti n ṣegbe ninu ẹ̀ṣẹ, ti a fẹ lati gbé ọla orukọ Ọlọrun ga lai wá ogo ti ara wa, ti a si mu iduro wa fun Ọrọ Ọlọrun lai gbọjẹgẹ pẹlu ẹnikẹni ti ko duro fun gbogbo ilana Ọrọ Ọlọrun.

**Idanwo Mose**

Ọlọrun maa n faye silẹ lati dán awọn iranṣẹ Rẹ̀ wo nigba pupọ ati ni oniruuru ọna. A le ro pe Mose ti kọ́ ẹkọ to laaarin ogoji ọdun ti o lò gẹgẹ bi ẹni ti yoo jọba lori ilẹ Egipti pẹlu iye ọdun kan naa ti o tun lo lati fi ṣe itọju awọn agutan baba iyawo rẹ̀ ni aginju. Lootọ ni Mose ni itẹsiwaju pupọ nipa ti ẹmi lakoko naa. Ẹni nipa igbagbọ́ ti o kọ awọn iṣura Egipti silẹ, ti o yàn lati maa ba awọn Heberu ẹrú ti a kẹgan gbe nitori o ri ibukun ti o tobi ninu ẹgan Kristi, ju ohun ti ayé yii lọ eyi ti o wà fun igba diẹ, o ti kọ́ ẹkọ ti isẹra-ẹni ninu aginju. Ni pataki, o kọ́ bi a ti i tẹle Ọlọrun lai sare kọja akoko ti Ọlọrun fẹ́. Eyi si jẹ ẹkọ kan ti yoo gba ọpọlọpọ ẹlomiran ju ogoji ọdun lọ lati kọ́!

Ṣugbọn idanwo ti o de ba Mose lakoko yii yatọ si ti igba ti o wà ni Egipti tabi ni aginju. Iṣẹgun ti Mose ni lori idanwo naa fi ẹmi ti o wà ninu Mose hàn: ẹmi iwa pẹlẹ ati irẹlẹ, ẹmi ifẹ tootọ si Ọlọrun ati ifẹ gbigbona lati gbe Ọlọrun ga ju ohunkohun lọ.

Nigba ti awọn Ọmọ Israẹli kùn si Mose ni Refidimu nitori wọn kò ri omi mu, wọn wi pe, "Ẽtiri ti iwọ fi mú wa goke lati Egipti wá" (Ẹksodu 17:3). Nigba ti wọn ni ki Aarọni ṣe ẹgbọrọ maluu wura fun wọn, wọn tun sọ ni ti Mose pe oun ni ẹni ti o mu wọn lati Egipti jade wá (Ẹksodu 32:1). Mose gba ọrọ wọn yii si ami ipo iṣọtẹ ti ọkàn awọn eniyan naa wà. Wọn ti pada kuro lẹyin Ọlọrun ati kuro labẹ iṣakoso Rẹ̀. Mose jẹ ki wọn mọ pe ki i ṣe oun ni wọn n kùn si, ṣugbọn Ọlọrun ni wọn n kùn si.

Ṣugbọn nigba ti Ọlọrun sọ fun Mose pe awọn Ọmọ Israẹli ti ba ara wọn jẹ́, wọn si pada si ibọriṣa, Ọlọrun funra Rẹ̀ pe awọn eniyan naa ni awọn eniyan Mose, O si wi pe Mose ni o mu wọn kuro ni Egipti. Ọlọrun sọ fun Mose pe ki o jọwọ Oun jẹẹ ki Oun pa wọn run patapata ki Oun si gbe orilẹ-ede miiran dide lati inu iran Mose iranṣẹ Rẹ̀ olooótọ. Ọlọrun i ba ṣe bẹẹ lai ba majẹmu Rẹ̀ pẹlu Abrahamu jẹ, nitori Mose jẹ iran Abrahamu, orilẹ-ede ti a ba si gbe dide lati ọdọ rẹ yoo jẹ ti idile Abrahamu sibẹ.

Ṣugbọn Mose kò dabi iru ọpọ awọn miiran ti i ba gba iru anfaani yii lati jẹ baba orilẹ-ède, ki gbogbo iran eniyan maa bu ọla fun un. Mose ro ti ọla orukọ Ọlọrun ju ati wá ọla ti ara rẹ̀ lọ. A ti ri i pe o sọ fun Ọlọrun ohun ti awọn ara Egipti yoo wí ati ẹgan ti iru iwa bẹẹ yoo mu bá orukọ Ọlọrun.

Idanwo naa ko i ti tán sibẹ. Ọlọrun yi pada kuro ninu ipinnu Rẹ̀ pe Oun yoo pa awọn eniyan naa run, O si paṣẹ fun Mose lati mu wọn lọ si ilẹ ileri nitori majẹmu ti O ti bá Abrahamu dá. Ṣugbọn Ọlọrun wi pe Oun ki yoo ba wọn lọ nitori ẹ̀ṣẹ ati iwa buburu wọn. O ṣeleri lati rán angẹli kan ṣiwaju wọn ti yoo le awọn ara ilu naa jade, ṣugbọn Ọlọrun kò ni ba wọn lọ ni irin-ajo naa.

Mose mọ ọkàn awọn Ọmọ Israẹli. O mọ̀ pẹlu pe ohun ti Ọlọrun kò ba lọwọ ninu rẹ̀ asán patapata ni, afi bi oju Ọlọrun ba wà lara wọn nigba gbogbo. O tun bẹ Ọlọrun fun awọn Ọmọ Israẹli, o si rán Ọlọrun leti irẹpọ timọtimọ ti oun ti ni pẹlu Rẹ̀. "Bi mo ba ri ore-ọfẹ li oju rẹ, fi ọ̀na rẹ hàn mi nisisiyi, ki emi ki o le mọ̀ ọ, ki emi ki o le ri ore-ọfẹ li oju rẹ: ki o si rò pe orilẹ-ède yi enia rẹ ni." Oun kò beere fun itọni, iranwọ ati agbara fun ara rẹ̀ nikan, ṣugbọn o tun n beere pe ki Ọlọrun le gba awọn Ọmọ Israẹli pada gẹgẹ bi eniyan Rẹ̀.

"Nipa ewo li a o fi mọ̀ nihinyi pe, emi ri ore-ọfẹ li oju rẹ, ani emi ati awọn enia rẹ? ki iha iṣe ni ti pe iwọ mbá wa lọ ni, bẽli a o si yà wa sọ́tọ, emi ati awọn enia rẹ, kuro lara gbogbo enia ti o wà lori ilẹ?" Alakoso tootọ ni Mose jẹ́, agbọrandun nla, ati olooótọ eniyan Ọlọrun! Oun kò jẹ ki igberaga tabi ifẹ ipo ati ọlá dí iṣẹ ti Ọlọrun fi fun un lọwọ. Iṣẹ rẹ̀ si Ọlọrun ni pe ki o mu awọn Ọmọ Israẹli lọ si ilẹ Kenaani ki i ṣe gẹgẹ bi orilẹ-ede nikan ṣugbọn gẹgẹ bi orilẹ-ede Ọlọrun! Oun kò jẹ ki ohunkohun fa ọkàn rẹ̀ kuro lẹnu iṣẹ rẹ̀.

Bi o tilẹ ṣe pe Ọlọrun fi igba gbogbo pe awọn Ọmọ Israẹli ni eniyan Mose, sibẹ nigbakuugba ni Mose sọ fun Ọlọrun pe eniyan Rẹ̀ ni wọn i ṣe, ati pe Ọlọrun nikan ṣoṣo ni o mu wọn jade kuro ni Egipti. Mose fẹ ki o di mimọ̀ pe awọn iṣẹ iyanu wọnni ki i ṣe ti oun bi o tilẹ jẹ pe nipa nina ọpa rẹ̀ ni a fi ṣe wọn. Awọn eniyan le yara gbagbọ pe Mose ni agbára awamaridi kan, gẹgẹ bi awọn eniyan ti maa n sé agbara Ọlọrun titi di oni yii, ti wọn si ro pe agbara airi kan ninu ọmọ eniyan tabi agbara kan ninu aye nipa iṣe ẹda ni o n ṣe iṣẹ-iyanu naa. Ṣugbọn Mose kò jẹ ki iru ero yi wà ninu ẹnikẹni nigbakigba ti ohun ti o jọ bẹẹ ba jade; nigba ti Ọlọrun paapaa tilẹ sọ iru ọrọ bẹẹ lati fi dán Mose wò, lẹsẹkẹsẹ ni Mose tun sọ eyi ti o tọ́ ti o si jẹ ki o di mimọ̀ pe eniyan Ọlọrun ni awọn Ọmọ Israẹli i ṣe, pe Ọlọrun ni o mu wọn jade lati Egipti ati pe awọn iṣẹ ami ati iṣẹ-iyanu ti wọn ti ri, ọwọ́ Ọlọrun ni o ṣe wọn. (Wo Ẹksodu 32:7, 11, 31, 34; 33:1, 12, 13, 16; 34:10, 27; Numeri 10:11-13, 33-36).

**Majẹmu ti a Sọ Di Ọ̀tun**

Nigba ti idanwo Mose pari ti awọn Ọmọ Israẹli si yi pada si Ọlọrun ni ironupiwada ati ikaanu fun ẹ̀ṣẹ ibọriṣa wọn (Ẹksodu 33:4), Ọlọrun fi ara Rẹ̀ hàn fun Mose ni ọna ti o pọ ju ti atẹyinwa lọ. Ṣugbọn ko ni itẹlọrun, o taku ti Ọlọrun, o n bẹbẹ fun ọpọ ibukun si i nitori awọn Ọmọ Israẹli, eyi ti o tubọ fi ẹmi aimọ-ti-ara rẹ̀ nikan hàn. Eyi ni

o mu ki Ọlọrun ṣeleri pe Oun o jẹ ki oore Oun kọja niwaju Mose, Oun o si pe orukọ nla Jehofa niwaju onirẹlẹ akikanju alakoso Israẹli yii.

Nigba ti akoko ti Ọlọrun to, o pe Mose sori Oke lẹẹkan si i lati mu walaa okuta meji pẹlu rẹ wá, lara eyi ti Ọlọrun yoo tun kọ ofin si. Lakoko ti Mose wà lori Oke fun ogoji ọjọ yii, o ni anfaani lati ri iriri ti o ga rekọja eyi ti ẹnikẹni ti ri lọ. Nibẹ, ati ni akoko naa ni a pe orukọ Oluwa niwaju Mose. Nibẹ ni eniyan Ọlọrun yii ni òye si i nipa ẹni ti Ọlọrun i ṣe, ohun ti o ja si fun eniyan, ati ohun ti o le ṣe fun awọn eniyan ti o bẹru Rẹ.

Nigba ti Mose pada de lati Oke Sinai o sọ ohun gbogbo ti Oluwa ti ba a sọ lori Oke naa fun awọn Ọmọ Israẹli (Ẹksodu 34:32), nibẹ ni awọn Ọmọ Israẹli kọkọ mọ̀ nipa iwa-Ọlọrun lorişirişi. Wọn ri i pe ki i ṣe pe Ọlọrun jẹ oloootọ nigba kan, ki O si wa jẹ alaanu nigba miiran. Wọn ri i pe ki i ṣe pe O jẹ ọlọgbọn ni igba kan O si wa jẹ Ẹni rere nigba miiran. Wọn ri i pe nigba gbogbo ni O jẹ oloootọ, alaanu, ọlọgbọn, ati Ẹni rere. Wọn ri i dajudaju pe Ẹni pipe ni Oun i ṣe lọna gbogbo ati nigba gbogbo. Wọn ti mọ tẹlẹ pe Jehofa jẹ Ẹni ti O wà fun ara Rẹ ti O pinnu lati fi agbara nla gba awọn eniyan Rẹ là (Ẹksodu 6:1), ṣugbọn wọn wa mọ Ọn nisisiyii gẹgẹ bi Olugbala ti O wà laaye ti O le dari ẹ̀ṣẹ wọn ji wọn bi wọn ba ronupiwada tọkàntọkàn, ati gẹgẹ bi Ọlọrun onidajọ ti o le jẹ wọn niya titi ayeraye, ti yoo si ṣe bẹẹ bi wọn kò ba ronupiwada.

### Titobi ati Ere ti O wà ninu Adura Ilaja

A mọ daju pe ko si ohun ti o le dá eto Ọlọrun duro, ko si agbara kan laye tabi lọrun apaadi bi o ti wu ki o tobi to ti o le di iṣẹ Ọlọrun lọwọ. A si mọ pe Ọlọrun le mu eto Rẹ ṣẹ lai si ẹnikẹni, bi ko ba ṣe e ṣe fun Un lati lo ẹni kan fun imuṣẹ eto Rẹ; sibẹ a ko le ṣai ronu lori ohun ti i ba ṣẹlẹ, bi o ba jẹ pe Mose ko fẹ lati gbé Ọlọrun ga ju lati gba ọla ayé yii fun ara rẹ. Angẹli Oluwa i ba ti lọ ṣiwaju awọn Ọmọ Israẹli lati le awọn ara Kenaani jade, awọn eniyan naa i ba ti tiraka lati tẹsiwaju ninu igbiyanju ati ailera ti ẹda lati de ilẹ naa, ṣugbọn Ọlọrun ki bá ti ba wọn lọ. A ki ba ti mú awọn walaa okuta miiran jade, ika ọwọ́ Ọlọrun kì ba si ti kọ Ofin mimọ Rẹ sibẹ. Boya a ki ba ti kọ́ Agọ ninu aginju, a ki ba si ti le ṣe irubọ wọnni fun idariji ati iwẹnumọ ẹ̀ṣẹ. A ki ba ti fi turari iyin jona lori pẹpẹ wura, bẹẹ ni Ṣẹkina ki ba ti wà laaarin awọn kerubu.

Bi Mose ko ba ti jẹ oloootọ si Ọlọrun ni ọna bayii, agbara nla ti o sọkalẹ nigba ti a pari Agọ kì ba ti jẹ ti Israẹli, bẹẹ ni akoso Ọlọrun kì ba ti si fun ogoji ọdun naa. Ki ba si ti si apẹẹrẹ fun awọn ti n ṣọtẹ si awọn alakoso ti Ọlọrun yàn, nitori ki ba ti si Agbara ni Israẹli lati bi Kora, Datani ati Abiramu ṣubu nigba ti wọn ṣọtẹ̀. A ba padanu apẹẹrẹ nla kan bi a ko ba ni anfaani lati ka iroyin awọn ami ati ibi ti o de ba awọn Ọmọ Israẹli nigba ti wọn gbiyanju lati lọ si ilẹ naa lodi si ifẹ Ọlọrun.

Ohun pupọ ni o rọ̀ mọ́ adura iṣipẹ wa, fun mimọ ifẹ Ọlọrun fun ayé ti wa, ati ti awọn ti wọn wà labẹ akoso wa. A dupẹ lọwọ Ọlọrun pe Mose faya rán idanwo naa! A dupẹ lọwọ Ọlọrun pe a sọ majẹmu naa di ọ̀tun! A tun dupẹ lọwọ Ọlọrun si i fun awọn ti n fi adura ṣipẹ̀ lati igba naa wa titi fi di ọjọ oni laaarin awọn eniyan mimọ́ ti wọn fẹ ki iṣẹ Ọlọrun gbilẹ, ki orukọ Ọlọrun si ni ọla ju ohunkohun lọ ni gbogbo aye.

Ijolootọ ninu adura iṣipẹ yoo gbà wa ni ohun kan, ṣugbọn ere pupọ wà nibẹ. Mose ri ifarahan Ọlọrun ti ẹni kan ko ri ri titi di igba naa, nitori oun nikan ni o goke lọ lakoko yii. Ati nitori oun wà pẹlu Ọlọrun pẹ́ to bẹẹ, awọ oju rẹ n dán fun ogo Ọlọrun, ti awọn Ọmọ Israẹli ti o kun fun ero ohun ti ayé yii ko le wò. Boya irisi Mose fẹrẹ fara jọ bi o ti ri ni Oke Ipalarada nigba ti o duro pẹlu Jesu lori oke kan lẹyin eyi (Luku 9:30, 31). Imọlẹ oju rẹ yii fi han awọn Ọmọ Israẹli igbega alakoso wọn nipa ti ẹmi. O tun fi han awa naa pe Ọlọrun le fi ogo Rẹ fun awọn ti o ri oju rere Rẹ (Ẹksodu 33:19). O n kọ́ wa pe idapọ ati irẹpọ gigun pẹlu Ọlọrun maa n mu iyipada ba onigbagbọ́ to bẹẹ ti oun yoo fi dabi aworan Ọlọrun Ọrun (Johannu 3:1-3).

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni ṣe ti a ni lati tún awọn walaa okuta ṣe ati lati tún wọn kọ?
2. Sọ ti idanwo nla ti a fi siwaju Mose gẹgẹ bi a ti kà ninu ẹkọ wa yii, ati bi oun ṣe fi iwa otitọ rẹ hàn si Ọlọrun.
3. Bawo ni Mose ti gba aawẹ ati adura pẹ to lori Oke Sinai lakoko yii?
4. Ki ni awọn ibukun nla ati iṣipaya Ọlọrun ti Mose ri gba nitori adura rẹ igba gbogbo?
5. Ki ni ojuṣe ti awọn Ọmọ Israẹli ni lati ṣe ki wọn ba le pa majẹmu ti a ṣe lori Oke Sinai mọ́?
6. Ki ni ṣe ti eto ti Ọlọrun fi lelẹ fun awọn Ọmọ Israẹli gbà pe ki a pa orilẹ-ède Kenaani run?
7. Darukọ akoko pataki mẹta laaarin ọdun nigba ti gbogbo ọkunrin Israẹli ni lati fara hàn niwaju Oluwa.
8. Eredi rẹ fun awọn ajọ mẹta nla naa?
9. Ki ni ogo ti o fara hàn loju Mose n sọ fun ni?
10. Sọ oniruuru iwa ati iṣe igbesi aye Mose ti o mu ki o jẹ alakoso ati iranṣẹ iyanu bayii?